IROHIN ABO ILU OYINBO AWON OLOTU WA



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

U. T. C. SERVES YOU WELL

VOL. No. IX "526. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JULY 6, 1957. KOBO MEJI (2)

## Ohun Ti Awon Iko Wa Mu Bo Lati Ilu Oyinbo

Ninu ipade igbimo ti awon se ninu ile egbe Lancaster lati ojo 23rd osu May si ojo 28th osu June 1957, nipa ofin titun fun ile Nigeria, nibe ni a ti se ipinnu wipe ki a se ipare ase Gomina ti agbegbe Iwo-orun ati ti Ila-orun ki o ma si mo. Ase oba ilu oyinbo ko ni mule mo lori awon ofin ti agbegbe mejeji ba se.

AWON OHUN PATAKI NIWONYI

1. Ijoba Iwo-orun ati ti Ila-orun ni lati di omnira arawon.
2. Koko-ase awon Gomina Iwo-orun ati ti Ila-orun ni lati pare.
3. Ijoba Ila-orun ati Iwo-orun nilati mo tele ki a to yan Gomina fun won.
4. Ko ni si ase Oba obinrin Gesi lori awon ofin ti awon ijoba mejeji na ba se mo ayafi lori awon nkan meta pataki :-
(I) Bi ofin kan ba nfe lo di si adehun ti a ba Gesi se (II) Bi a ba fe fi etanu se ohun ti o lodi si Ijoba Gesi tabi si alejo ti ko ngbe ile Nigeria, (III) Bi a ba fe se ohun ti o le fa Ijoba Nigeria sinu ewu.
5. Gomina ko ni si ninu igbimo mo awon Prime Minister ni yio ma se alaga igbimo.
6. Attorney - General yio ma se ise labe ijoba Iwo-orun ati ti Ila-orun ninu ile ise re, ko si ni lo si igbimo awon Minister mo.
7. Ealti o ba joye Gomina ni yio ma fi oata joye adajo kekere.
8. Ilu Eko ni kan ni ao ma joye Prime Minister, ao ni ma pe awon Prime Ministers to mbe ni Iwo-orun, Ila-orun ati nile Hausa ni Primiers.
9. Sekitari agba ti tiko, ati Sekitari ti o ntoju owo kan ni si ninu igbimo mo.
10. Nigbati o ba di asiko erun ti odun 1959, ki a se itoka igbimo

(Wo yoku loju ewe keje)

## Afin Oba Ilu Oyinbo



Ile nla ti a nwo ninu aworan yi ni nwon npe ni Buckingham Palace. Gbogbo awon oba ti o ti nje nilu Gesi ile ti nwon ngbe ni yi, eyiti o nje lowo-lowo yi, ibe na lo ngbe, Awon ti yio si tun je lehin re ibe na ni awon ma gbe. Gegebi iga Idoluganran ti je fun oba Eko ti o je wipe gbogbo oba ti o ti nje ni ohun ti o bere lori oba Ado titi o fi de ori oba Adele keji ti o nje lowo nisisiyi, bena ni ile ti a nwo yi je fun awon oba ilu Gesi. Bi Afin Buckingham ti je ile ati ibugbe fun awon oba Gesi, beni Iga Idoluganran, ko nse dukia enikan, ibugbe lo je fun gbogbo awon oba ilu Eko.

LYONS ICE CREAM

| | |
|---|---|
| EGE NLA (Big Vanilla Bars) | 4d |
| EGE NLA ONI-SOKOLETI (Choc Ices) | 6d |
| EGE TI O TO FUN O ATI EBI RE (Family Bricks) | 2/2d |
| EGE TI O TOBI-JULO (WONDER Cakes) | 5/6d |

Je Igbadun Re Loni





# Ilu merin lo wa l'ere-kusu Iddo

EKO. Awon Arakin so fun wa pe, Ado ni awon ara ibiol npe ni Iddo. On ni eniti o sigbo wa lati Iseri ni-kori iberu Ogun Egba, Ijebu ati papaa Ogun Idahomi, o si te do si erekusu Iddo. Ibiti Ado ngbe lasiko na ni apa ibiti awon Olopa ko ile si ni tosi ile moto ti (Zarpes). Awon agba so fun wa wipe eniti o ba bere Oju-egun ti Ado Olofin nibiti a gba wi yi, nwon o fi han a.

Ilu kan tun wa labe Agbo̩o ti nwon npe ni abule Ogun-jasa. Okun-rin ti a daruko yi je Balogun fun Ado. Ilu Ora lo wa nibiti awon U.A.C. gbe nkan oko, ilu miran ti o tun wa nibe ti a npe bio beni okun si tun wati a npe ni Ijora.

Ado ni iru agbo tutu kan lowo lasiko na ti o je wipe, bi o ba te igbale bo o, ti o si fon danu si ogun kan, jini-jini yio ba ogun na.

Ise ti Ado ni, lati ma so ogun Bini ti o ba mbo lati ona Langba-sa, ise ti Ogun-jasa ni lati ma so awon Egba ati awon Ijebu bi nwon ba nyole bo ise ti Olnto ni lati ma so awon Awori ati ara Ora bi nwon ba mbo. Ise ti Ojora ni lati ma so awon Egun ati Idahomi bi o ba mbo wa, ju gbogbo re lo, Ado yi na ni gbogbo won gbekale.

# Oba Jebba si ile Bure-di titun

JẸBBA. Laipe yi ni ọba ilu Jẹbba ti a npe ni Malam Amọdu, ei eti odo Ọya, ni apa Iṣalẹ (South) si ile ero ti a nṣe buredi titun, eyiti a npe ni Seguaro Prime Bakery ti Ibajoko rẹ wa ni adugbo kan ti awọn npe ni Okeyare.

Ọba na so wipe, ìsu on dun jojo lati ri wipe, awọn ọmọ wa ti o ti lẹ kọṣẹ nilu okere, ti npada wa nile lati wa gbe ọjọ ilu wọn ga. Iyi nla ni lo si tun jẹ lati ri wipe Dawodu ọba Ilọrin lo wa si ile na nilu yi.

Iyin ati ọpẹ nla lo fi fun ọgbẹni Seguaro lati jẹ akọkọ ninu awọn ẹnia ti o wa se iru iṣẹ yi si arowoto wa. Eyiyi si jẹ iṣiṣẹ kini ninu ara awọn lẹ ti awọn ọmọ wa mbo wa de ile wa.

Ọpọlọpọ ẹnia lo wa sibi iṣile na lati ọna okere bi Eko, Ibadan, Offa, Osi, Sare, Oke ọdẹ Omu-aran, Sadu ati lati Kutawenji.

Njẹ iwọ Seguaro Prime Bakery, o ko ni ṣe e ti o.

# Ati goke, ko to ati sokale

ILỌRIN. A gbọ irohin wipe, ọkan ninu awọn ti o mọ nkan towa ninu ilẹ, (Geologist) ti o lọ si apa ilẹ Ilọrin gbidanwo lati gun ori oke Ṣọbi ni ilu Ilọrin. Nigbati o ngun, fẹrẹ, fẹrẹ lo fi nṣe, o kan fẹ gun lati fi ṣe idaraya ni, nitoripe oyinbo ti nwọn ba lọ si tẹ koiri de nwọn rangẹ pe o ni Ibadan, o si wi fun awọn ọmọ rẹ pe ki nwọn ma niṣo de on nidi Oke Ṣọbi, ki nwọn pagi sibẹ de on, nitori bi on ba mbọ lati Ibadan, tara ibẹ, on mbọ.

Ọkunrin yi goke de ori Ṣọbi tan, o se ohun ti o fẹ ṣe; ṣugbọn ati sọkalẹ wa di ẹti, o dabi enipe Oke na tunbọ ga soke, gbogbo ọna ti o gba gun ori oke yi di eyiti o nyọ bọrọ-bọrọ.

O bẹrẹ si kegbe si awọn ẹnia ti o mbẹ, bẹni awọn ti o wa nilẹ ko ri oju ẹniti o npe wọn, awọn ko roju ibiti o gba gun'ke. Nwọn wa ju okun si nigbati Oyinbo wọn de, okun yi lo ba sọkalẹ. Ilu owe lo npa dọkọ-dọkọ, ilu ale lo npa fala-fala, afẹjudi lo npa ọmọ kekere.

# Benson Jare



Ogbeni T. O. S. Benson

Aworan ti a nwo yi niti Ọgbẹni T. O. S. Benson ti ọdọmọbinrin ti o si nfẹ nilẹ yi ri, ti lẹ gbe iyawo arede pọ pẹlu Dokita Ṣolanke, ni okẹlẹ nilu Oyinbo, ti o si ko Benson sinu wahala ọjọ ole wipe o ji agogo ọrun-ọwọ ati oruka arede ti ọkọ on ra fun on.

Irohin kan wa wipe Ọgbẹni T. O. S. Benson jare ọjọ na ni Kotu George nilu Oyinbo ni ọjọ Monday ọsẹ yi.



# Ewu lo l'ori okunrin kan

AMẸRIKA. Irohin kan wa wipe, ni ilu New York, ọkunrin kan pẹlu iyawo rẹ ati awọn ọmọ rẹ wọ ọkọ reluwe ti o nrin labẹ ilẹ. Nibiti awọn joko si inu ọkọ, nwọn ri apo iwe kan ti nwọn di kurudu bi eyiti nwọn 'gbagbe sinu ọkọ. Ṣamọ-ṣamọ, iku ṣẹnu boro ni nwọn joko ti.

Nigbati ọkunrin na ma sọkalẹ, o rope nigbati ẹnikan ko wijọ wipe ti oun ni apo na, o mu lọ sile tirẹ. Nigbati o de ile, o da a silẹ, o si ba olifo agolo Salmọn ati Sardini larin awọn agolo nwọnyi ọkunrin na ri ẹtu oloro (Bomb) kan.

Ọkunrin na tete fura si, nitoripe, o ti ri iru rẹ ri lasiko ti o nṣe iṣẹ ṣọja, o kegbe si iyawo rẹ pe, ki o yara ko awọn ọmọde salọ ilna rere, o n papaa sare lọ pe awọn ọlọpa, o si rohin ohun ti o ri fun wọn.

Ni kia-mọsa awọn ọlọpa ti de ibẹ, nwọn rora fi ṣọ gbe ẹtu oloro na lọ jina rere, ibẹ ni nwọn ti ṣakiyesi wipe, iru ẹtu oloro kan ti nwọn npe ni Oxygen Bomb ni. Bayi ni ewu lọ lori ọkunrin na.

# Ika Ko Dara, Ika Ko Sunwon

Gbẹna-gbẹna to wo apata kọrọ, kini yio fi ṣe, ani, emi ni yio fi ṣe? Aṣẹ i awọ tẹrẹ to bo inu ni ko jẹki a ri ikun aṣẹ lohun?

Ile ti a fe akuko ko de inu, ibi ki a pa a jẹ lo mọ. Awọn ika ko fẹ ki aru ẹru ki asi ọ kalẹ ṣe eri ẹni lo nsọ ni.

Aṣa ko ku, ara ko rọ Ẹtu, ẹiyẹ Awodi n'vo Igbin kọrọ Igbin ha nṣe onjẹ ẹiyẹ bi ? Epe ibinu ko apa Odi, Ọlọrun iba da kanyinkanyin ko ninla bi ẹṣin, atapa ni iba tani Atapa ni iba ṣaṣin.

Adiẹ iba ni ọkọ, iba fi atitan ṣe nkan. A ko nda ọmọ oku ọrun 'loro, a ko nṣeka fun ọmọ orukan nitoripe o yẹ ki a ma fi ọrọ ro ara ẹni wo. Eyiyi ko nṣe imọran ika rara, ẹ ma si ṣe ṣi,pẹ nsro fun Abuke.

# Ohun ti o wu mi ki nje laiye

Olotu,

1. Ohun ti emi fẹ ki njẹ ni ti emi ni wipe mo fẹ ki njẹ oye Popu (Pope nigbana emi ko ni jẹ ẹlẹṣẹ mọ, nko si ni ma ṣe aṣiṣe kan, nitoripe, a sọ fun wa pe Popu nikan ni ẹniti ko le ṣe aṣiṣe nile aiye (Perfect) bi mo ba ku lẹhin na tara Jerusalem Titun ni ngo ma lọ. Ngo jere laiye ngo si jere lọrun.
2. O wa mi ki njẹ Ọba, nkan-ki-nkan ti o ba wu mi ni ngo ma daṣẹ le, ṣe ṣayin na ti mọ pe ohun ti ọba ba daṣẹ le di tirẹ auni.
3. Mo nfẹ ki ndi Arabe, Igbakeji Alapini emi yio ni agbara Ọkunrin-Ogun ngo ni oriṣiri ogun ija lọwọ, ngo lọ sigbo Erin, ngo pa erin, ngo lọ sigbo Ẹfọn ngo pa ẹfọn ngo pa Arọni baba wọn, okiki mi yio ma kan gbo-o ngo pa Ajẹ, ngo pa olobi pẹlu.

Emi ni,
Adediran Ile-oluji

# Onigbese GoGi Orun

IBADAN. A gbọ irohin wipe ọkunrin kan ti o fẹ ṣe gbajumọ, nigbati ko lowo lọwọ, ṣe fari lọ si ṣọbu awọn oyinbo oniṣowo Faranse ti a npe ni S. C. O. A. o si ra mọto kekere kan ni ọrinle-lẹgbata-lemarun Pọun, o si ṣe iwe owo (cheque) fun wọn, le ba gbe mọto, on ati iyawo rẹ ati ọmọ rẹ, o di ilu Eko lo bẹrẹ si ṣe faaji ti o nmuti kiri.

Ṣamọ-ṣamọ, oloro ko ni epinni aladọjọ ninu Benki, iwe aramu kanda lo ṣe fun wọn. Nigbati ọrọ yi di mimọ, awọn oyinbo Oniṣowo bẹrẹ si lepa rẹ kiri nigbati nwọn ri, nsu aje ṣe wọn, nitori o ti lo mọto na ni ilo ti owo ni ko si ni bẹ.

Nwọn le jade, nwọn si gba mọto nidi rẹ pada lọ si Ibadan, nwọn fun ṣe, nwọn si ta a ni ẹdinwo adọtale - nirinwo Pọun, nwọn si wa pe ọkunrin na lọ si kotu fun Pọun marun - dilogoji - lerugba ti o ṣeku ki o to pe oju owo sinu kotu.

A tilẹ gbọ wipe ese ni ọkunrin na tilẹ wa jingiri ohun-kohun ti o le tidi rẹ bọ, ko bikita mọ, o ni ki adajọ ṣe on bi o ba ti fẹ, nigbana ni adajọ ṣe idajọ le lori bi o ti tọ.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi lede fun gbogbo enyin Aṣoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Ọya, nile Ibo, l'oka Okun ati nibi Oyinbo wipe ẹnikẹni ti ko ba fi owo wa ranṣẹ so kọ ọrọ rẹ fun Loya Eleti-Ọfẹ, so ba ṣe ẹlọ so si gba owo irin ẹṣẹ lọwọ wọn.

OLOTU


## Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, [illegible] oniruru ojaṣe [illegible] tobinrin. Tete wa ra tiẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos



## CARSON PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENTS:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, BALOGUN STREET, LAGOS

# ELETI ỌFẸ

A-NIU-WỌN KO SE WI L'EIJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI-ỌFẸ LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23270

VOL. IX. NO. 527. LAGOS, SATURDAY JULY 6, 1957


## OTE EKO PARI, ABUSE–BUSE

Ọtẹ Eko ti pari, abuṣe si ti buṣe. L'ọsẹ tokọja ni a gbọ irohin ikẹjọ ẹjọ Ige Idunganran, ẹjọ na ti mbẹ nilẹ to iwọn ọdun mẹjọ sẹhin, oriṣiriṣi ija, tẹmbẹlẹkun, adakoyede ati ọpọlọpọ rogbodiyan ni ẹjọ yi ti fa silẹ, ni arin ẹgbọn si aburo, larin baba si ọmọ, larin iyawo si ọkọ rẹ.

Adupẹ ti awọn ọjọgbọn, awọn ọgbọnkangi ninu ofin ati asa isọdajọ nile Oyinbo, ti fi eti bale gbọ bi ẹjọ na tiri, ti nwọn si gbe yẹwo s'ọtun, s'osi, siwaju ati si ẹhin, ti nwọn si da are fun alare ati ẹbi fun ẹlẹbi.

Nitorina, o tọ, o si yẹ, ki olukuluku wa fa ọkọ rẹ si itọ, ki a si gbagbe ohun gbogbo ti o ti rekọja lọ ni okun igbagbe, ki a sowọpọ m'ojuto iṣẹ ilọsiwaju ilu wa gẹgẹbi gbogbo wa ti nlepa Ominira fun ilẹ wa (Nigeria) bi orilẹ ede.

### ABỌ ỌRỌ TO FUN OMOLUWABI

Enikẹni ninu wa ti o ba ni anfani lati ka ọrọ ṣoki ti Ọmọba Adeyinka Oyekan kọ sinu iwe irohin tabi eyiti nwọn ba ka si leti, yio ki o rowu mọ wipe nwọn igbati asiko ti to lati pa ọrọ fun rare lati sọ wipe on yio yọ ọrọ kuro ninu apọn tiko yọ, on yio si gberuku ti ire ilọsiwaju ilẹ wa l'ẹhin, eyi tito ẹkọ fun gbogbo wa.

Nitorina, ọtẹ Eko ti pari, abuṣe si ti buṣe.


### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO NIKAN, FUN IGO KAN)

O wa lọdọ:—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
19, VICTORIA STREET, LAGOS


## Olorun Ko Gbami Ku-rọ Lowo Jamba

ILU Oyinbo: Ọrọ ti a ko mọdi ki Olorun ma-sa fi se konge eni. Awon Gesi ati Rosia mba ara won soro irepo Rosia ranse si Gesi wipe on yio wa be ilu London wo, Gesi si gba ba lati gba won ni alejo.

Nigbati nwon de, oko ogun rabata kan ni nwon wo de nwon si duro ninu agbami odo Thames. Ni asiko yi, ni ogagun womi-womi kan wo inu omi lo aitosi ibiti oko ogun Rosia duro si, A lo ni a ri a ko abo re mo. Ko si ibiti awon Gesi ko wa oku womi-womi na de, sugbon nwon ko ri i. Nwon bere lowo ogagun oko Rosia bi o ba mo ohun kan nipa ogagun na, nwon dahun wipe ndao, awon ko mo ohun kan nipa re.

Lehin osu merinla, ti nkan yi ti sele ni nwon ri oku womi-womi kan ti ko ni ori, awon Gesi gbe oku na, nwon se iwadi nipa re nwon si ri pe oku na je ti ogagun Lionel Buster Crabb.

Awon Gesi ko le gba gbe akinkanju ti ologbe Ogagun na se lasiko ogun Jamani keji o pa itu meje ti ọdẹ apa o si se gudugudu meje pelu.

## Isokan Nigeria Ni A Fe



Ile ti a ba fi otito ati ododo bere re e daju wipe, nwon a ko ile na d'opin. Awon asiwaju wa ki nwon to lo silu oyinbo isokan ile Nigeria ni nwon gbe sokan lo bi a koiti ri ominira gba eyiti a ri gba dun mo wa jojo.

Ogbeni Lennox Boyd so wipe Gomina agba ati awon Gomina kekeke metata awon egbe N.P.C. awon U.N.I.P. gbogbo won lo fara mo eto egbe Afenifere kilo ha ti je ti awon egbe kan fi ko lati fara mo egbe Afenifere? Bi oro na ba dabi iro e wo aworan awon N.P.C. ati Action Group lati owo osi Malam Ribadu, C.D Akran Alhaji Ahmed Sardauna Oloye Awolowo ati Oloye Rotimi Williams.

# Ere Emotan



Ere to duro ti a nwo aworan yi ni ere Emotan ti Agbegilere kan ti ko nse omo ile wa nihin gbe lati fi se ohun oso si arin ilu Ibini, oruko re je John Danford.

Ohun pataki ti nwon se titori re gbe ere na ni wipe, awon opitan so wipe, nigba laelae ti ogun mbe kakiri, obinrin kan ara ilu Bini ti nwon npe ni Emotan lo segun ogun na. E yi nidi re ti a se gbe igi lere re ti nwon si gbe duro si arin ilu Bini.

Nigbana ooikeal, ti o ba sĳu lo wo ere na nibiti o gbe duro si lo ma niran Emotan olugbala ilu Bini. Ogbeni John Danford na ni a nwo nipa aworan yi nibiti o nfi oda kun ere na.

# Omobinrin kan puro mo Agutan

Nigbakan iya kan ti nwon npe ni Gbemigbola, o si ni agutan kan ti o nsin ati omobinrin kekere kan ti nwon npe ni Moni.

Nigbati Iya yi, Gbemigbola, ba nlo si oko, yio fi Moni ati agutan s i l e sile. Ki o to pada de, gbogbo eran inu obe ni Moni yio ti wa je tan yio si fi epo pa agutan lenu. Nigbati Iya won bade ti o bere tani ko eran obe je, Moni yio wipe agutan ni, e wo enu re, Iya na yio si bere si lu agutan.

Agutan na fere ku nitori lilu ojojumo yi, nigbati o nfe ku ni Olorun fun ni oro so bayi pe, Moni lo te owo epo bo on lenu. Ha, ha, ha eranko soro.

Nje iru agutan ti o nsoro yi ko ye ki a so mole n s e ni ki nwon fi sile k'o ma rin kiri tabi ki a pa a ki a je. Mo nfe esi lodo enyin okawe wa.

Emi ni,

Solomon Ajagbe

# Igbomina Je Oba Ilu Osi

ILORIN Edekoyede tabi gbon'mi-omi ori ko ti ti be sile larin awon omo oba ilu Osi lori eni ti yio je oye tabi a ko je oye. Awon enia meji lo ndu oye oba ilu Osi, enikini awon apakan fe yan ni oba yato si eniti oba Ilorin fe yan.

Owe Yoruba kan so wipe bi ile ba da si meji, ti oba ni ao se. Oba Ilorin ti nse ijoba nu gbogbo roghodiyan na dopin, nipa fifi ase ijoba yan okunrin kiri o kan ti a npe ni Ogbeni Ezekiel Afolayan s'ori oye oba Osi na, o si jawe oye le lori.

Lehin ti nwon ti yan oba tan, ni oba Ilorin wa fi oro le fun won pe, "O di owo nyin o, enyin omo oba, Oba titun ti o je yi, ori ko gbodo fo, edo koegbodo dun. Sugbon ohun ti on fe ki nwon se ni wipe, ki nwon ni ifowosowopo pelu re, ki Alufa A l a b i Olaruko o b a l o s i s m i, ki o fa oba titun mora, ki irepo si wa larin ara won, eyi ni nkan ti on Oba Ilorin fe. Olorun ko ran nyin lowo o.

Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks

& Building Materials

PLEASE CONSULT :

Okunowo Brothers

63 Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

Hear your favourites!

INSTRUMENTALISTS

SINGERS

DANCE BANDS

on

Yellow Label

RECORDS

Recorded in West Africa

Sold by all the best stores

"HIS MASTER'S VOICE"

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# Ekemiran yio joye Aboke

IBADAN. Agbo wipe, iya Oke ugola ti o ti je o e Aboke, ebi enin yio ma se etutu ododun moi Orisa Oke Ibadan salaiti eti wio, ni asiko ti awon Egungun tatafo si ojode Olubadan ni awon o si paya oruko eni ti awon o tun fi joye Aboke l'odun ni.

Awon Opitan so wipe Alkatun ti o wa njos Oke-Ibadan yi, je eyiti o to ti ti mu re kokan gun to emo ni iduro. Eyi nidi re ti nwon fi nki boyi pe Oke Ibadan olomu oruba.

Nigbati enikan ba fe ko omo jade ninu Ibadan lehin ti awon ba ti pari etutu isomo-l'oruko tan awon enia yio ma korin bayi wipe:-

E ba mi gb'omo Oke
Lanti, lanti.

Ninu osu April ni awon mbo Oke-Ibadan, awon obinrin lo si ni awo yi. Nwon gbagbo pe, obinrin ti ko ba ri omo bi, ti o si fe omo, bi o ba tele Iya Aboke kakiri ilu, o daju pe omo ni yio gbe jade ni amodun. Eyi nidi re ti awon obinrin se npo ninu ijade Oke Ibadan Orisa:-

Iya ma ba mi wi,
Aboke ni mo ba r'ode.

# Ile ibiti a gbe nda aso



Nile Oyinbo, ninu ile ibiti nwon nran aso, nigbati nwon ba ran aso kan pari tan, awon o nd ki obran ninu awon omo akeko ti o wa nibe gbe aso na wo, lati wo bi o ti dara to,

Awon ti a nwo yi ni awon omobinrin akeko ti o nko ise aranso labe Madam Netalie Neymar ninu ile ise re ti o mbe ni Mayfair. Orisirisi awon omo akeko lo wa sibe kakiri agbaiye.

Awon ti a nwo ninu aworan yi, lati owo osi, Felicia Alonta, Ghana, C. Isted, England. U. Cher, Australia, M. Komar, Poland, L. Cordier, France ati J. Wadis, India.






## O Ye Ki Owu Ba Oke - Onigbin Wa Ni Irepo

OLOTU. Gba mi laye ninu iwe irohin re lati da si oro edekoyede kan ti o be sile larin awon Kiriyo ati Imale Owu. Oko oba ko ni sa nyin lese o.

Mo fi iwe yi ke si enyin agbalagba ilu Owu ati enyin ijoye ati gbajumo, o ye ki e tete dasi oro ti o sele larin awon Kiriyo ati awon Imale, nitoripe, ko si ohun ti o dabi ife, ninu ifowo-sowopo ni ilu ndagba s'oke.

Lehin ti a ti pari oju ona moto lati Oke Onigbin lo si ilu Owu tan ni odomode ati agbagba ilu Owu ti bere si da owo kan jo ni Poun kokan enikan, ibere wa ni wipe owo na tile di elo ti nwon da? A si fe ki e fi ye wa kini ohun ti e fi owo na se? a nreti esi ki oro na to di giga.

Emi ni,
R. A. Jay
ara ita Ma rtins

## Woli Aje pania

PEKING. Ni ilu kan ti a npe ni Peking nile Saina, awon obinrin arugbo meji kan ti nwon npe ara won ni Aladura ti nwon si npolowo Omi mimo kakiri.

Nwon wo aso funfun bi awon Aladura awon wo bata funfun, nwon si gbe agbelebu funfun dani, ati tesuba funfun, ibori won funfun, nwon si fi ibowo funfun s'owo, gbogbo enia ti e ba pade won lo nfi towo-towo ki won; nwon si npe won ni Woli, iranse Olorun.

Bi nwon ba gbe alaisan wa, awon a se adura sinu omi nwon a si bu etu die si, nwon a ni ki alaisan na gbe mu. Ko riju wakati kan lo, alaisan na yio ku. Nigbati awon enia ti o oku nipa omi-mimo yi se lo bi mejidilogun, ibe ni ara na fu awon olopa, nwon si ra awon Aje Woli meji na mu, nwon si wa ni itimole nisisiyi.

# Awon Minister ti o nlo si Meka



Ni gere ti awon Iko deblade lati ilu Oyinbo, ni awon enia ti o je Musulumi ninu won gba ko alon oko ti awon fe lo bi eiye lati ba won gun ori oke Arafa ni odunni.

Awon ti a awo ninu aworan yi ni Malam Sardauna Sokoto, Prime Minister ile Oke Oya, on le wo lawani. Ekeji ni Ogbeni Adegoke Adelabu ti o nse olori awon Alatako nilu Ibadan, on le de fila gobi.

Awon ti o tun nlo si ilu Meka lati lose Hadji pelu awon enia nwonyi ti awon jijo woko ofurufu kanna po ni, Alhadji Muhamed Ribadu Alhadji Inua Wada, Malam Tafawa Balewa ati Malam Isa Kaita.

Alo a dara, abo ananwon o.



OGBENI A. ADELABU

## Adura Pataki

Ni enanri, tabi inu rirun ba nyo enia lenu, jeki o tan ina abela, ki o si ma korin bayi pe:-

Iku rekoja lo

Iye re o, iku fo amedi na ylo si fuye.

# E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.

# Ohun ti o wu mi niyi

OLOTU,

Gba mi laye lati so fun opo bere ka iwe irohin Eleti-Ofe nipa ohun ti o wu mi lati je.

1. O wu mi ki nje Agbe, lojojumo ninu oko mi ni ngo wa, ko ni si ariwo Moto, ko ni si yago lona fun mi koja, ngo si ma je eso ti o ba wu mi.

2. Mo fe ki nje ara oko, ngo ma sun fa a, ngo si ma je ni akoko ti o wu mi, ki atoji, omi amala ti de ori ina, obe gbegiri ti nse koto-koto.

3. O wu mi ki nje enia Olorun, lati ma sin Olorun ninu iwa mimo, ki nsi ma je onigbowo lati ma bebe fun elese.

Emi ni,

Alufa Alafia taye ara Ejigbo

"The English Association of Accountants & Auditors. The English Association of Estate Agents & Valuers. The English Association of Secretaries.
Founded 1941. Membership on Professional Experience, or Certificates with Reputable Schools, Colleges, Universities".
9 Charles St. Newport, Mon. Eng.

SECOND-HAND CLOTHING:-

| | |
|---|---|
| Women's Long Overcoats | 2/6d. |
| Women's Short Coats | 1/6d. |
| Women's Dresses and Frocks | 1/- |
| Women's Skirts | 1/- |
| Men's Overcoats, | 6/- |
| Men's Raincoats, Cotton and Gabs mixed | 2/6d |
| Men's Jackets | 2/- |
| Men's Waistcoats | 6d |
| Men's Felt Hats | 1/- |
| Police Helmets | 1/- |

Prices quoted ex Warehouse C.I.F. charges extra.
Wholesale quantities only.
Immediate attention. Write for full price list. Organs £10. Radiograms £10. Pianos £10. Typewriters £10. Sewing Machines £10.
H. NEWMAN & CO. (MERCHANTS) LTD.,
88/92, ELIZABETH STREET, MANCHESTER, ENGLAND.

No. 90

# WAGES BOARDS ORDINANCE 1957

## Commission Of Inquiry Into Retail AND ANCILLARY TRADES IN THE FEDERAL Territory of Lagos.

It is desired to bring to the notice of the general public that public sittings of the Commission of Inquiry into the Retail and Ancillary Trades in the Federal Territory of Lagos, will commence in the Committee Room of the House of Representatives Lagos, on Monday 15th July, 1957.

2. The Commission is charged with the investigation of the wages and the machinery for regulating wages or other conditions of employment of workers engaged in the retail and ancillary trades in the Federal Territory of Lagos, with particular reference to the following questions;

(a) whether or not wages are unreasonably low;
(b) whether or not there exists adequate machinery for regulating the wages or other conditions of employment;
(c) whether or not the existing machinery, if any, is likely to cease to exist or cease to be adequate for that purpose.

3. The Commission will recommend whether or not a Wages Board in respect of the said workers and their employers should be established.

4. Any person or body of persons desiring to submit written representations to the Commission is invited to do so between now and the 15th of July; and any person or body of persons desiring to give oral evidence before the Commission is invited to communicate with the Secretary.

Representations and any other communications for the Secretary should be sent to the address given below.

H. M. KASUMU
Secretary to the Commission.

Department of Labour,
Central Office,
Ikoyi Road,
Lagos.

NI IRANTI
IYA WA OWON

Jane Loko

Eniti o dapo mo awon Mimo ni ojo keji osu July 1955.
Sun're, Mamma wa; Sun're.
AWA OMO RE

## IROHIN ABO ILU OYINBO

(O bere lati oju kini)

House of Representative
11. A ni lati da igbimo ijoba miran sile ti ao ma pe ni Senate ao yan enia meji-meji lati ilu agbegbe kokan. Oba Eko ati awon enia meta lati Eko ni lati wa ni be, ki a si ton yan awon enia merin miran. Ijoba agbegbe kokan ni yio yan eniti o ba wu won lati mu lo si igbimo Senate. Sugbon eniti nwon o yan si igbimo na ni lati dagba to omo ogoji odun.

12. Awon igbimo yio se eto ayo ile'bo si ona oria-din-nirinwo (320) ti yio je ti enia kokan ti ao ma dibo fun.

13. Ni agbegbe Iwo-Orun ati ni Ila-Orun t'okunrin-tobirin ni yio ma dibo, sugbon nile Hausa, awon okunrin nikan ni yio ma dibo.

14. Sekiteri ati Sekiteri owo ti Kaduna ko gbodo lo si ile imo mo.

15. Ki a da igbimo awon Oloye sile ni agbegbe Ila-orun ki nwon si lagbara lati da ofin duro fun osu mefa.

16. Agbegbe kokan lase lati ni Banki tire ti o ba fe.

17. Agbegbe kokan lase lati ni olopa tire lototo, bi Sekiteri ilu oyinbo ba gba be.

18. Oba Eko ni ko ma se baba egbe fun igbimo Lagos Town Council.

(Iyoku di ose to mbo.)

No. 92

# TRAFFIC NOTICE:
# Eid El Kabir - 8th July, 1957.

The attention of all car owners and drivers is invited to the following Traffic Arrangements operating on the occasion of the Muslem Festival on Monday 8th July, 1957.

(a) VICTORIA STREET will be closed to vehicular Traffic as from 0700 hours but might be opened from time to time if circumstances permit.

(b) TRAFFIC ENTERING LAGOS via Carter Bridge after 0700 hours will turn right into John Street at the War Memorial and proceed thence via Bishop Street to the Marina.

(c) NORMAL TRAFFIC ENTERING LAGOS from Ikoyi will be diverted via St. Gregory's Road and Onikan Road as from 0730 hours.
This diversion might be necessary in the reverse direction at any time between 0730 hours and 1300 hours.

(d) ONE WAY TRAFFIC will operate in Onikan Road Westward to the junction of King George V. Road.

(e) ALL HEAVY TRAFFIC will leave Obalende Praying Ground via the Macgregor Canal Bridge.

(f) IGBO STREET AND OJO STREET will be closed to Traffic; Procession Traffic will enter via Deffi Street:

**J: T. C. Denley A. S. P.**
OFFICER - IN - CHARGE,
MOTOR TRAFFIC DIVISION, LAGOS.

## Orisa l'omi Osie

ENUGU. Irohin kan wa wipe, omi ti ijoba Ila-Orun gbe oro afami si, aino eyiti nwon ti nfa omi jade wa fun gbogbo enia mu nilu Enugu, ko ni lati ko si sipe ki o to gbe, nitorina, nwon tun gbe oro afami won lo si odo kan ti o wa ni Ongo ti nwon pe ni Ose.

Awon ara ilu yi taku wipe ijoba ko gbodo fa omi nini odo won, nitoripe orisa won ni tabi bawo ni orisa wa yio ha tise di agbegbe lowo ijoba baun?

Agoju ijoba si ladi oro na" ye won ni tanbi-nubi wipe, Oke-marun enia lo ngbe ilu Enugu oni ti nwon si nmu nisisiyi ko to nkan. Bi o ba le jebi ijoba fa omi lodo orisa nyin yi, ohun ti ao si la oju ona si arin odo na ti ge ma gba koja.

Ko si enikan ti o le so ysio awon enia na y'o gba, tadani ba si jo fun ijoba wipe ki nwon lese wa odo miran, nitori ko si omi pupo ninu eyiti nwon gbe oro afami si.

## Koto Se Idajo Onilegbale

EKO Iyalin Fafunke omo Onilegbale lo pe ejebon re Oloye Onilegbale lejo si Kotu G nran, nipa oro ile kan ti o wa ni No. 18, Onilegbale Street ni Eko.

A gbo wipe Iyalin Funke jegun ile ti a wi yi lati odo iya re ti o ti ku pe ni Okilu. Lehin eti adajo gbo oro tonun ati ti tan, o dahun pe on ko ri ejo ijare kankan ni gbogbo oro ti Oloye Onilegbale so, on ko si ri idi re ti o se ailati de ibi ile na mo.

Nigbati eniti o fi ile na lo l'ore ba si mbe laye, ti bi ewo, ti omo re si mbe laye, ko si ebi kan ti o ni eto lati de ibi ile na.

Nitorina Oloye Onilegbale jebi oro yi ki o lo san Poun mewa fun owo nkan ti o ba je nipa ile na, ki o lo san Poun mejala ati pilo mesan fun nkan onikan ti o lo yoju si o si fe lwa ejo Iyalin Fafunkeya, nitori eyiti o so pe ki adajo fi eniti o ni ile na han.

93.

# Vacancy

Applications are invited for the post of Executive Officer, Grade One, Nigerianisation Office.

**Particulars in Government Notice No. 1135 in the Federation of Nigeria Official Gazette of the 20th June, 1957.**






Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23310